Itiju wa ninu igbagbọ

Lati ọdọ Abdullahi ọmọ Umar- ki Ọlọhun yọnu si àwọn mejeeji- o sọ pé: Anọbi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- gbọ ti arákùnrin kan n ṣe wáàsí fun ọmọ-iya rẹ nipa ìtìjú, o wa sọ pé: “Itiju wa ninu igbagbọ”.

[O ni alaafia] [Ohun ti wọ́n fi ẹnu kò lé lórí ni]

Anọbi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- gbọ ti arákùnrin kan n gba ọmọ-ìyá rẹ ni imọran pe ki o fi àpọ̀jù itiju silẹ! O wa ṣàlàyé fun un pe ìtìjú wa ninu ìgbàgbọ́, ko si lee mu nǹkan kan wa ayafi oore. Ìtìjú jẹ iwa kan ti o maa n mu èèyàn ṣe dáadáa, ti o si maa n mu èèyàn fi ohun buruku silẹ.

http://sunnah.global/hadeeth/yo/show/5478